# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 756, WEDNESDAY. JULY 29, 1964 (2D)


## Enia Mọkanlelogorin Ku Ninu Jamba Ọkọ Oju Irin

PORTO:- Jinijini dabo gbogbo enia nigbati ariwo ẹkun bo gbogbo awọn to wa ni ilu Porto lẹba Portugal ni ọjọ Aje ti işe ọjọ kẹtadinlọgbọn oşu yi nigbati awọn enia ilu na gbọ pe Ọkọ oju irin kan danu.

Nigbati irohin na de etigbọ awọn enia ilu na ni nwọn kọ gbọ pe enia mọkanlelogorin lo kọkọ ku ninu awọn ọmọ ile ẹkọ ti nlọ fun isimi ti awọn enia na gbọ pe ọkọ oju irin na danu ni alẹ ọjọ Aje ti işe ọjọ kẹtadinlọgbọn oşu yi

Gegẹbi ọrọ ti ari gbo lati ẹnu agbẹsọ fun ile iwosan Antonia fi ye oniwe irohin wa to wa ni Porto pe awọn enia mọkanlelogọrin ninu wọn mọ pe o ti ku patapata ni ile iwosan wọn ati ni ile iwosan miran

Agbẹnusọ fun ile iwosan na tun sọ pe awọn ko ti mọ iye enia to farapa ninu awọn enia to wa ninu ọkọ oju irin na

Awọn enia ni nwọn ti o fara pa na to bi ọgọrin si ọgọfa enia to farapa tojẹ pe awọn enia to fara pa nasi wa ninu ewu

Awọn Ọlọpa to nşişẹ nibi ti jamba ọkọ oju irin na ti şẹlẹ si nşişẹ bayi gẹgẹbi ọkọ oju irinna yio şe le bọsi oju irin

# ILE IGBIMỌ AŞOFIN APAPỌ YIO HA TUKA NI OŞU KẸSAN ỌDUN YI BI ?

KADUNA:— Ni ọjọ Aiku ti işe ọjọ kejidinlọgbọn oşu yi ni Olori ẹgbẹ N. E. P. U. ati alaga ẹgbẹ N. P. F. Alhaji Aminu Kano fi nye awọn oniwe irohin ni Kaduna pe on gbọ pe nwọn yio tu ile Igbimọ Aşofin fu Apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ka ni oşu kẹsan ọdun yi.



Oloye S. L. Akintọla

Olori ẹgbẹ NEPU na nsọ eyi nigbati on ba awọn oniwe irohin nse ipade ni ilu Kaduna nigbati o fẹ lọ si Jos ni Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria lati Jos ni Alhaji Aminu Kano yio ti mura rẹ lati wa si Eko ni ọjọ'Bọ ti ise ọgbọnjo Oşu yi.



Alhaji Aminu Kano

Alhaji Aminu Kano tun fi ye awọn oniwe irohin pe oda on loju pe gbogbo ijoko ibo to wa ni Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria ni awọn ẹgbẹ wọn ti nwọn sẹsẹ da silẹ lenulọlọyi eyiti orukọ ẹgbẹ titun na njẹ Northern Progressive Front (NPF) Alhaji Aminu Kano tun nsọ ninu ọrọ rẹ fun awọn oniwe irohin pe gbogbo ẹgbẹ oselu to wa ni ipinlẹ Ariwa ni o papọ di ẹgbẹ NPF ati pe orukọ ẹgbẹ na ni awọn yio fi dibo si ile igbimọ aşofin apapọ Ijọba ilẹ Naijiria jakejado ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria.

### IDARU—DAPỌ

Alhaji Aminu Kano tun fi ye awọn oniwe irohin pe ko si nkan to ba ofin mu lati ri pe ẹgbẹ Afẹnifẹre tabi ẹgbẹ Alakukọ N C N C tun fẹ mu enia silẹ ni Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria laijẹ pe wọn lo orukọ ti ẹgbẹ titun ti nwọn da silẹ ni Ipinlẹ na tabi ki o jẹ pe awọn ẹgbẹ Oşelu na yio tun gbe apoti ibo miran silẹ eyiti yio yatọ si ti ọmọ ẹgbẹ wọn NPF ati pe gbogbo awọn ẹgbẹ na ni Ipinlẹ Ariwa lo ti şe adehun lati jẹ ọmọ ẹgbẹ kan na

Olori ẹgbe N E P U Alhaji Aminu Kano tun fi ye awọn oniwe Irohin pe ohun to tọ to si tun yẹ ki awọn olori ẹgbẹ Oşelu ilẹ Naijiria şe bayi ni pe ki nwọn tete ri pe nwọn din awọn ọmọ ẹgbẹ Oşelu to wa ni orilẹ ede ilẹ Naijiria ku patapata Alhaji Aminu Kano tun şe alaye pe ti nwọn ko ba din awọn ẹgbẹ Oşelu na ku Alhaji Aminu Kano sọ pe ko si igba ti idaru-dapọ tabi rudurudu ko ni ma bẹ silẹ ni orilẹ ede Naijiria



Alhaji D. S. Adegbenro

Alhaji Aminu Kano tun sọ siwaju si pe eto ẹgbẹ oşelu to ti pọ ju ni ilẹ Naijiria ati awọn ọpọlọpọ ti awọn enia ilẹ Naijiria ko ti fi ibo gbe wọ ile Igbimọ Aşofin lo pọju.

Ninu ọrọ Alhaji Aminu Kano tuu sọ fun awọn oniwe Irohin ni Kaduna ni pe on ri daju pe awọn ọmọ ẹgbẹ wọn ni ipilẹ Ariwa ilẹ Naijiria yio bori ibo si ile igbimọ Aşofin eyiti nwọn yio şe idibo rẹ laipẹ yi.



Alhaji Abubakar

Alhaji Aminu Kano tun sọ ninu ọrọ rẹ fun awọn oniwe Irohin pe ohun to mu awọn ẹgbẹ oşelu to wa ni ipinlẹ Ariwa papọ ni pe lati le ri pe eto Ijọba rere wa ni ipilẹ na ati lati jẹ ki eto ofin rere wa ni ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria.

WO OJU EWE KẸFA



Dokita M. I. Okpara

# IJINLẸ LARIN IKU ATI IYE

Ohun ijinlẹ to wa larin iku ati iye je ohun ti ẹda ko le sọ rara. O si jẹ ohun ti Ẹlẹda enia fi edidi di gboyingbọyin. To bẹ o sọrọ lati ye enia, Ti a ko ba ni purọ lori ọrọ yi. A ko ni ri na lati ladirẹ fun ẹda alaye bi iye ati iku ti ri.

## Lati Ọwọ S. O. JAIYE

Ohun pataki to wa ni pe awa bi ẹda nsun a si ma la ala wipe a lọ si ibi bayi ati lẹhin na awa sare soke sodo ninu ala wa. Ṣugbọn ko si ẹniti o le wipe nigbati on la ala on pẹlu ọrẹ on tabi iyekan on wa pẹlu on pẹlu ọmọ rẹ.

Emi ko gbọ eyi ri pe o ri bẹ. Ti aba wa ninu orun ti ko ba le fun wa ni apẹrẹ ọrọ iku; melo melo ni apẹrẹ iku papa fun ara rẹ, Ki a to lọ siwaju a o sọ diẹ ni pa aidaniloju nipa ohun to ṣẹlẹ ninu orun tabi ninu ala wa

Nigba miran ẹda a ma la ala pe on fo kiri ni awọsanma tabi pe ki ẹnikan ma le kiri loju ala Nigba miran elomi ama le nkan kiri,

To bẹ ti owọ rẹ le to nkan to fẹ ṣugbọn miran inu oluwa rẹ. Yio dun pe ọwọ on ba ohun ti on fẹ Ṣugbọn nigbati o ba taji awa ri pe asan ati imulẹmofo ni gbogbo nkan ti on ṣe ayọ le wa lori ala rẹ.

Ninu ala wa a ko fiye wa gbangba pe bi irẹpọ ti wa larin on ati ọmọ pẹlu aiya wipe on ni iba lo pọ ninu ala on. Mo tun fye si pe ẹlẹda wa papa le ma ba ni sọrọ loju ala n'nu orun wa, Lehin eyi o tun ma bani sọrọ nipa iriran, ninu ilaju silẹ kedere. ohun pupọ ni a le ma wo, ṣugbọn nigbati o ba ṣe ti a ri nkan lulẹ a le ta gir to bẹ ti iye wa yo soji sinu aiye. Ọna kẹta Olọrun la ran ara si ara ẹni nipa lile loye.

Gbogbo awọn ọna mẹta yi ko fi han wa wide bayi ni ọrun yo ri tabi lẹhin iku irẹpọ kan yo wa larin awọn ọrẹ si ọrẹ tabi ara si ara. Gbogbo awon woli ati onișẹ Ọlorun to wa saju ko si okan to ṣe apejuwe bi iye ati iku to wa si. Ẹnikan na ni mo ro pe o sọ fun wa dẹ nipa Ọrun Jesu to wipe ile Baba mi ọpọ ibugbe lo wa ni bẹ ati pe on lo pese aye silẹ fun ni

Iru Ibugbe na ko ye ni dada to. A fi ti a ba ti ọkan igbagbọ gbaa wipe bẹ ni ori . Ni idakeji Jesu sọ fun wa pe ni Ọrun lohun. ni a ko gbe iyawo bẹni a ki



Ọgbẹni S. O. Jaiye

fi ọmọ fun ọkọ.

Nitori gbogbo nwọn yo dabi angeli. Eyi nipe ko si akọ tabi abo. Ti a ba fi oju ẹmi wo a o ri pe awọn to ba ni anfani lati wọ ile ti Jesu wi ini yo ni lati yatọ si iru ẹda ti awa ninu aiye loni yi.

Ohun ijinlẹ ni eyi, ko si ẹda kan to le ya aworan bi ẹda yo ti ri lẹhin iku nitori ko si ẹda to ri angeli ni ẹya pipe bi enia,

Mo ro pe apẹrẹ iye ati iku wa ninu ọgbin ti a ngbin ninu oko. Bi eku ti njade ninu ohun ọgbin ati bi ẹhu ti ṣe ko bẹrẹ oṣoro fun wa pupọ lati mọ,

Bi irugbin ti a gbin ko to yọ ehu jade ko tilẹ so bi iparada rẹ ti ri irugbin titun to bẹrẹ si gbinlẹ bẹni ẹda ko le sọ iku ati iye la ra imọ enia,

Ọrọ iye ati iku jẹ awamaridi ni. Ti ẹ'a ba le mọ idi ohun meji Daju ẹda ni lati mọ ogun aiku Ohun ti a ba mọ bọ ti ti se wa ni lati mọ idi bi a o ti ṣe atunṣe rẹ,

Gẹgẹbi ọkunrin Kọssia na ti wipe on de agbegbe oṣupa ṣugbọn o ko gburo Ọlọrun. O jẹ ohun erin fun emi alaimọkan pe ọjọgbọn ati akọni ọkọnrin. yi nreti Ilẹ Ọlọrun ninu ofurufu.

Nigbati Ọlọrun paya wa ninu on papa. Ko tilẹ yẹ pe iye wa ninu rẹ gegebi iku yo ti yọ si ni ọjọ kan tuyẹ.

Bi enia ko ti mọ igba ati iṣẹju ti orun mu on lọ papa bẹni ẹda na ko le mọ bi iye ti ri ninu i besi aiye on, Bi iye ti ṣe wa ninu gbogbo igi e eso ati koriko lasan bẹni o tun wa fun enia gbogbo.

Bi ẹda ko ti mọ ọjọ iwaṣẹ iye ẹai bẹni ko le mọ iwakati tabi iṣẹju kiku ẹni. Bi ati mọ wipe orungbẹ lo nṣaju orun bẹni aisan ati eṣe ninṣe atọkun iku,

Nigbati awadi idi eyi ati iku o wa han kedere pe ko si ẹni o wa laye ti o le sọ bi ohun ijinlẹ to wa larin iye ati Iku. Ṣugbọn ohun to daju nipe ohun awamaridi kan wa larin Iku ati iye.

Ẹni ti o ba le mọ ohun ijinlẹ yi o le ri Ọlọrun kedere loju koju. Nitori pe iku iku. Aimọ to wa larin awọn mejeji yi ni ohun ijinlẹ ti a mọ ni ohun ininlẹ ta bi awamaridi.

Ko si ohun ti a le tun fi e apẹrẹ ju awọn nkan swọnyi lọ, Ti ohun aimọ n

ba wa ti mimọ ba si wa, Njẹ nitori na k a maṣe wa di nkan ṣoṣo mọ,

Ohun awamaridi ni Ko si ohun awamaridi kan ju Ọlọrun lọ. Nitori na ni a ṣe pe iṣe Ọlọrun ni awamaridi ati pe ko si ẹniti o ni ohun iṣika ohun meji yi lọ ju Ọlọrun papa fun ara rẹ lọ

Edidi Iye ti Ọlọrun fi di iye ni ko jẹ ki iku ri iye bẹni iye ko le ri iku afi ki iku parada si ajinde ti iṣe iye ninu Ọ l ọ r u n. Ti a ko ba ni se ahesọ irọ ohun ijinlẹ ti o wa larin iye ati iko mo ro wipe nibẹ ni imọ adi itu Ọlọrun wa

idi yi nipe o fi soro fun ẹniti o wa ninu iye lati mọ ohun ti o wa ni arin Iku ati ẹniti o wa ninu Iku lati mọ ohun to wa ninu iye

Papa gidi Ọlọrun ko fi asiri yi han awọn ti o wa lọdọ Rẹ li Ọrun. Idi na ni Jesu papa wipe igba opin aiye ko si ẹniti o mọ igba na ati akoko rara

Bakanna ko si ẹda ti yo le mọ igba iku rẹ. Ṣugbọn Jesu papa ni ajinde ati iye Ẹnikẹni ti o ba gba O n gbọ bo tilẹ ku yo si ye Ami

Fun idi eyi gbogbo olugbagbọ ninu Jesu ni ireti iye lẹhin iku. Ohun ti mo ro pe o jẹ ipari ọrọ ni eyi lori Iku ati Iye.

O di gba diẹ.


# I C. M. Tọniki (100 Tabletș)



Gbiyanju lati ma lo I. C M. TỌNIKI nigbagbogbo I· C. M. TỌNIKI o wa fun Ọkunrin, Obinrin ati Alaboyun pẹlu. I. C. M. Tọniki o dara fun aini ẹjẹ to lara, o nfun ni lagbara, o si ntun ẹjẹ ṣe daradara. Bere fun eyọ igo kan, tabi dọsini. edidi Apo ( 50 dozes ) wa pẹlu. Iler i gun ọrẹ o Bere lọwọ Elẹ gi ynbo ti o wa ni adu e rẹ fun I. C; M TỌ KI (100 Tablets.)

Tabi ki o wa si ọdọ:—

MOSỌBALAJE MEDICINE STORES,
37, Palmchurch Sreet, LAGOS

# VE SI OLOTU

## Ęsę Ko Gbodo Parę Rara

no torę gafara lati dahun si ibere Ogbeni Orlando Babs bere ninu iwe oyin akomo lede to bere pe: Nję o yę ki a ęsę rę ? Ni ọkan temi ere eṣę jija ko gbodo parę ni ilę ati pe ti ęnyin Onkawe Irohin Imolę ba nri pe ere ęsę ti o je pe awon omo ilę wa mo pupo ju ninu gbogbo on nse kakiri ilę agbaaiye.



KOFO MOSES
Elęsę Obinrin

Ti ę ba lo ranti awon opolo- o awon omo ile Naijiria eyi to pe here ninu ere eṣę na ran won bi enia bi Horgan Bassey Dick Tiger, Rafiu King Joe, Sugar Ray Adigun ati awon he- ę to je pe nwon ti rin jina ninu ere eṣę jija ati pe ninu ere ti awon omo ilę Naijiria nṣe ohun niflan ni nwon ti gbayi ju to ba ba je ere Bolu yi nwon ko pe nbori wa ati pe ko si eni to le fi oju di wa nipa ere ęsę rara ni orilę agbaiye. Nitori eyę ere jija ko gbodo parę ni ilę wa rara.

Emi ni
Jimoh Elemo

Onupo

## Agbadun Eletu Odibo Ati Edet

Bi omo eni ba dara ę jeki a so pe, o dara,sugbon ki ise pe, ki a fi ṣe aya.

A gbadun Oloye Isola Bajulaiye Eletu Odibo Eko ati Gbakaji (Prime Minister) Oba Eko. Alaye ti ose fun wa nipa eto ayeye isinku Olola Oba Adeniji Adele Keji ti ewo aja laipe ye wa yekeyeke. Ninu ero Asoromaghesi (Radio) ni oti ṣe alaye na fun wa ni ojo Abameta ti ise ojo keringdinlogbon osu keje Odun yi.

A si tun gbadun Ogbeni Edet Oga awon Olola. Mo si fila, mo berę sa. Fun ękunręrę alaye ti o ṣe nipa iṣę awon Olopa ati nipa

iranwo ti awon nfę lodo awon ara ilu Naijiri.

Emi ni,
Alhaji Y. A. Disu
EKO.

## Oja Titun Fun Eko

Olotu,

Irohin Imolę, Inu mi o dun pupo ti ę ba le gba mi ni aye ninu iwe yin yi lati ki minista alamo buto eto ilu eko ati Alaga. Ijoba Ibilę eko fun ti oja titun ti won si fun ilu eko.

Irohin koto afojuba ni ayeye laa wo sise oja ebute ero na' opolo po owo si ni Ijoba na fun oja yi akana ni oja na ba oju mu, A dupe lowo yin o, e seun.

mo si tun ki gbogbo eyin ologja na, e ku wahala ojo na, a o ma a o mora mi si gbogbo enyi ti yio ma taja ninu oja titun yi ni lati ri pe, a teki oja na wa ni mimo' ki eleyi tun le ma fun awon ijoba ibi le eko ni iwuri nla, e jeki gbo gbo ibi wa ni mimo, e fun oja yin ni imoloto.

E mase jeki awon wole-wole Omo so fun wa nipa pe gbogbo nkan ti agba nta nibę ti o be je jije ni ki o ma wa ni mimo o.

Emi
Wosilatu Alake
EBUTE ERO

# I C. M. Tọniki (100 Tablets)

# Fi



Gbiyanju lati ma lo I. C. M. TONIKI nigbagbogbo I. C. M TONIKI o wa fun Okunrin, Obinrin ati Alaboyun pelu. I. C. M. Toniki o dara fun aini eje to lara, o nfun ni lagbara, o si ntun eje ṣe daradara. Bere fun eyo igo kan, tabi dosini, odidi Apo (50 dozes) wa pelu. Ilera ogun oro o Bere lowo Ele gi eynbo ti o wa ni adu o re fun I. C. M. TO KI (100 Tablets.)

Tabi ki o wa si odo:—

MOSOBALAJE MEDICINE STORES,
37, Palmchurch Sreet, LAGOS

Sunday 10/ fine next mont

GBOGBO ARA ILU NKO ORIN IYIN ati AYO NIPA "DYNAMIREN" TONIKI



ALE-BI-ELE Egbogi Toniki Jamonu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mo daju fun Ako agbara ati Ajebidan işę Rę lara Agbalagba Okunrin gbogbo'

Bi arę ara ba nmu o, nigbakugba fun wahala lala şişęşę,ti o ko ie jeun daradara, tabi ki o male sun daada okun losan tabi loru tabi awon işan ara rę gbogbo ki şe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlę daradara won işę tabi wahala şişe tabi fun awon alera gbogbo 'nyin ti ojo ori rę (age) ba ti koja Ogbon odun o si de adorin tabi jubę lo. Mo du o "DYNAMIREN" ni egbogi ti e nfę lati so ara di otun patapata anu rę a si jolo, eran ara rę ti o ti hunjo yio bi ę s'i do dada. Ara rę yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arę" ngbakugba yio salo pelu igoaba dun ati alafi diro de o. Iyeo daju. Bere Egbogi na ni Şobu: awon

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos.
hone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

IŞĘ

ATI NI AWON ŞOBU
OLODUMARE DISPENSARY
IBADAN

# IJ Odugbesan Ko Ọmọ Jade

..IGA:– Idunnu ṣubu lu ayọ ni ọjọ Isẹgun ti ise ọjọ kẹrindinlọgbọn Osu yi nigbati Ọgbẹn M.A Odungbẹsan akọwe agba ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ward 28 Ikẹja Sonth Constituency nse ẹyẹ ikomọ rẹ titun ti Oluwa fun on pẹlu iya afin Odugbẹsan.

Ọjọ ẹyẹ ikomọ jade Ọkunrin titun na jẹ ọjọ kan ninu igbesi aiye Ọgbeni Odugbesan ati iya afin Odugbesan Ni irọlẹ ọjọ Abamẹta ti ise ọjọ kẹdọgbọ Osu yi ni awọn ẹbi, ọrẹ ati awọn alabasẹyẹ Ọgbeni Odugbẹsan ti nde si ile Ọgbẹni Odugbọsan ni adugbo nomba 13 Adesina street B rigu, Shomolu

Nigbati o di agogo mẹta owurọ ọjọ ẹyẹ isọmọ l'orukọ na ni awọn si fun ọmọ kunrin jojolo na ni orukọ Adegboyega Adesina

Nigbati o di nkan bi agogo mejila ọsan ọjọ na ni awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre lati ilu miran bi Aba ni ipinlẹ ila orun Naijiria, Eko, Ikẹja, Ijẹbu-Ode Agọ-Iwoye Ibadan ati ọpọlọpọ ilu mura ti aye kosi lati daruko wọn

Nigbati odi nkan bi agogo marun irọlẹ ci eto ẹye isọmọ lorukọ na bẹrẹ pọlu ọpọlọpọ ọrọ iwuri lati ẹnu Ọgbẹni L .A Ọlaiya ti ojẹ Alaga ẹgbẹ Afẹnifẹre n ward 27 Ikẹja South Constitueucy

Ọgbẹni Odugbẹsan si fi jẹ ati mimu tẹ awọn enia o wa sibi ẹyẹ ikọmọ jade lọrun eyi ni d ẹ ninu awọn enia jankarjankan to wa si bi ẹyẹ ọjọ na ni Ọgbẹni L.A Ọlaiya Alaga ẹgbẹ Afẹnifẹre ward 27 Ikẹja South Constituency, Ọgbẹni F olu Alasẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre lati Aba ni ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria.

Ọgbẹni J.M K ..ralawọn Alaga ẹgbẹ Afẹnifẹre fun Shomolu ati agbegbe rẹ W A Osholakẹ akọwe agba fun ẹgbẹ Afẹnifre ni Shomolu ati agbegbe rẹ, Iya afin C A Ogunfowoke Iya ẹgbẹ awọn Obinrin ẹgbẹ ọmọ Oduduwa Iya afin kọgbọ Iya ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Shomolu ati agbegbe rẹ Ọgbẹni E A Matan-

WO OJU EWE KARUN

# YE IRAWỌ RE WO

AQUARIUS (Jan 21 – Feb 19) Ọna ara kan yio ṣi silẹ fun ọ lairotẹlẹ iwọ yio si gbadun ere faaji kan ti yio ṣẹlẹ lalẹ oni si ọ.

PISCES (Feb 20 - Mar 20) Ọpọlọpọ ohun ti o ti gbero lati ṣe ni iwọ yio yẹ silẹ ni iru akoko kan ti o ma nde si ọ nigba kọkan.

ARIES (Mar 21 - April 20) Akoko kan mbọ ninu eyiti a ti ṣa li ẹṣa fun ire ati anfani rẹ lati bẹrẹ, idunnu ati ayọ yio de si ọ ni aṣalẹ oni.

TAURUS (April 21 - May 22) Ikanju ati iyara gaga nikan lo le mu ọ ra ọja ti iwọ ko fẹ ra, ṣugbọn akẹhinsi rẹ, ire ni yio ja si.

GEMINI (May – June 21) Li akoko yi, ṣi pa ọrọ ile ti si ẹgbẹ kan na, ki o ma a ro bi iwọ yio ti ṣe nipa riri ile titun lati gbe, iwọ yio si ri opọlọpọ iranlọwọ nipa rẹ.

CANCER (June 22 – July 22) Ija kan yio ṣẹlẹ nibi kan ti o jẹ wipe ija na yio ra ọ lọwọ, ra ọ lẹsẹ, ohun to yẹ ọ lati ṣe ni ye ki o joko rẹ jẹjẹ ma woran, ki o ma si ṣe da si ọran na.

LEO (July 23-Aug. 22) Tunbọ jẹki gbajumọ rẹ gboro siwaju, bi o ba ri imọran ki o gba a, ki o si ma fun ni, ni imọran pẹlu, ki o si jẹki gbajumọ rẹ ga

VIRGO (Aug. 23-Sept. 23) Ni alẹ ti o ni iwa jẹjẹ lo yẹ ki iwọ pẹlu olufẹ rẹ ma hu, ẹ ko gbọdọ ba ara nyin ja,

LIBRA (Sept. 24-Oct 23) Maṣe gba eṣu laye lati gba ọna idẹra kuro lọwọ rẹ, nṣe ni ki o fi ẹsẹ rinlẹ gbọn ngbọnin.

SCORPIO (Oct. 24-Nov. 22) Ọpọlọpọ ireti rẹ, dabẹni pe ire ati anfani mbẹ ninu rẹ lati ọdọ ọrẹ kan, ti o jẹ tirẹ, ṣugbọn o yẹ ki o tọju owo ọwọ rẹ.

SAGITARIUS (Nov. 23-Dec. 21) Owo kan ti o nreti, yio pẹ jọjọ ki o to ni owo na gba, Ija kan ti o ti wa nilẹ fun ọjọ pipẹ, yio fẹrẹ da ọta si arin iwọ pẹlu ọrẹ rẹ kan.

CAPRICORN (Dec. 22-Jan. 20) Ipade kan ti iwọ ba wọn ṣe loni yio ba nkan ti o ti gba lero jẹ.


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Firms Patroise* MODUPE PRES *Becuase Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs;—*
Just Call 21985 – Leave the rest to Modupe

We Granantee Neat Work And Quick Service

**Modupe Printing Press**
16, Bamgbose Street
Phone 21985, Lagos.



..NGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!!




Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ e lenu on akan bi ọdun kan tabi jube lo awọn egbogi rọ irọbi fun le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara, Ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun I otutu, Ikọ ọna ofun, Iko Igbaaya, Iko iil. Ikọ ti o mọ mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungsa tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba an Igo kan PORAL yi wa Iwọ na yio ri iya tọ ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaya tabi ona ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara iwọ yio si sun fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orisiri i l ẽb gi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:—

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọjalta Faji) .... ....
Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba

# Okotie Eboh Ati Francicois Fi Okuta Ile Iṣẹ Ibode Lelẹ

IDI-IROKO:- Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogun Oṣu yi ni Oloye Festus Okotie-Eboh Alakoso eto iṣuna ilẹ Naijiria ati Ọgbẹni Francosi Aghogan Alakoso eto iṣuna ati eto Idagbasoke ti Ijoba ilẹ Dahomey ti Okuta ile iṣe ibode ti ipilẹ Naijiria ati Dahomey lelẹ ni oju ala ti ilẹ Naijiria ati Dahmey ni Idi-Iroko.

Ki eto eye ifi Okuta ile na to bẹrẹ ni awọn Ọlọpa ti ilẹ Dahomey si ti bẹrẹ si fi ere ati ilu da awọn enia lati ile Naijiria ati Dahomey lara ya ti awọn Ọlọpa ile Dahomey na tan fi orin ilẹ mejeji tun nda awọn enia ilu mejeji ni lara ya pẹlu.

Gbogbo awọn enia ile Naijiria ti nwọn gbe ilu Idi-Iro ati awọn enia lati ilẹ Dahomey lo si pesẹ sibi eyẹ ifi Okuta ile na lelẹ ti gbogbo ibi eyẹ na si kun ṣoṣo pẹlu Ọba ilu Idi-Iroko na lo si wa sibi eyẹ ifi okuta ile na lelẹ

Ni deede agogo mesan ku iṣeju mẹta ni Alakoso eto iṣuna ati Idagbasoke Ọgbẹni Francois ti ilẹ Dahomeyde ibi eye ifi okuta ile na lele pẹlu Alakoso ile miran lati ilu Dahomey si ba Francicois de ibi yẹ ifi Okuta ile na lelẹ.

Ni deede agogo mesan ku iṣẹju mẹta na ni Alakoso eto iṣẹ fun Ijọba Apapọ Oloye J. M. Johnson na de ibi ẹyẹ Ifi okuta ile na lẹlẹ pẹlu iyawo rẹ iya afin John.

Lẹṣẹkẹṣẹ na ni Oloye Festus Okotiẹ-Eboh Alakoso eto isuna fun Ijọba Apapọ ile Naijiria na de pẹlu Iyawo rẹ Iya-afin Okotiẹ-Eboh ti Alakoso eto iṣuna na si ki gbogbo awọn enia to wa sibi ẹyẹ na ni ede Yoruba pe Eku arọ o" lẹṣẹkẹṣẹ ti Oloye Okotiẹ-Eboh de ni gbogbo awọn enia to wa sibi yẹ na si lo joko lori yoko wọn.

Lẹhin eyi ni Alaga eto owo ibode fun ile Naijiria Ọgbeni Ayọdele Digan si ka eto eye ikini ku abọ fun awọn enia to wa sibi ẹyẹ na lede Geesi eyiti nwọn tun sẹ itumọ rẹ lede Faranse fun awọn enia ilu Dahomey

Lẹhin ti Ọgbeni Ayọdele Diyan ka eyẹ ikini ku abọ yi ni Oloye F S. Okotiẹ-Eboh ti o je Alakoso eto iṣuna fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria tun ka awọn ọrọ iwuri fun awọn enia to wa sibi ẹyẹ na lede Gẹsi eyi ti nwọn si se itumọ rẹ lede Franse

Ninu ọrọ Oloye Festus Okotiẹ-Eboh fun awọn enia ilẹ Naijiria ati Dahomey si sọ pe ajumọṣe pọ eto ile iṣe ibode yi yio mu irẹpọ ati isomọpọ wa fun ilẹ Naijiria ati ile Dahomomey ati pe yio si din iwa ole ati fayawọ ku ni orilẹ meji ni ati pe on ki egbe Alakukọ fun Ọla ti nwọn da on lati le jẹ ki on wa gẹgebi Alakuso eto isuna ilẹ Naijiria ati fun ọla ti Iijọba apapọ ile Naijiria fun on gẹgẹbi on ṣe wa bi enia kan ti yio fi okuta ile iṣe na lele o si tun dupẹ lọwọ awọn enia ilẹ Dahomey fun isowọpọ ti nwọn ni pẹlu ilẹ Najiria lati le jẹ ki eto ifi Okuta ile na lẹle yori si ere ati papa julọ Ọgbeni Francois ti o je Alakoso eto isuna ile Dahomey.



**Oloye Okotie-Eboh**
Minista alamojuto eto Inawo Apapo Ijọba

Lẹhin ti oloye Festus Okotiẹ-Ebo pari ọrọ rẹ tan ni Alakoso eto isuna ati idagbasoke ile Dahomey tun fun awọn ilẹ Naijiria ati *D*ahomey Francicois ni ọrọ wuri eyi ti Ọgbẹni Francicois ka ni ede Faranse ti nwọn si sẹ itumọ re lede Gẹsi.

Ninu ọrọ rẹ Ọgbeni Francicois si dupẹ pupọ lọwọ Ijọba ilẹ Naijiria ati papa jul Oloye Festus Okotiẹ-boh ẹe ẹbi ileri ti o ti ṣe larin Ọdun to koja eyi to si mu sẹ nipa isọwọpo eto ile ise Ibode ilẹ mejeji na eyi ti Ọgbẹni Francicois sọ pe Oloye F.S Okotie Eboh si ti sọ pe awọn ile Naijiria yio se iranlọwọ na fun orilẹ ede meji na

Lẹhin ti Alakoso eto isuna ati idagbasoke ilẹ Dahomey pari ọrọ rẹ ni awọn Alakoso meji na si fi okuta ile isẹ na lelẹ Ijọba orilẹ ede meji na si fi jijẹ ati mimu tẹ awọn enia to wa sibi ẹyẹ na l'ọrun eto ẹye ifi okuta ile na lelẹ si pari ni deede agogo mọkanla abọ owurọ.

Lati Oju Ewe Kẹrin

mi ọkan ninu ẹgbẹ Afenifẹre Ọgbeni M Ọla Akinsayan J A Abiodun Olu Fadipẹ T Ademola Ashimi ati ọpọlọpọ enia ti aye ko gba lati ka oruko wọn

Ọpọlọpọ awon enia to tun wa de sibi ẹyẹ na nkan bi agogo mẹjọ alẹ Awọn Alaba ṣẹyẹ ọjọ na si gbadun ọjọ na Ki Oluwa fi ohun rere kari wa amin

The best watch in its class




S. A. AJIBỌLA & S N
279, L. E. D. B. Shops,
Imman Ligali Street,
Akanni Area,
LAGOS.



IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO AWA

No. 756 WEDNESDAY JULY 29. 1964 2D

## Ọkunrin Kan To Ji Mọto Bọsi wọ Ẹwọn Ọdun Mẹta

EBUTE- MẸTTA Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlogbọn oṣu yi ni Adele adajọ agba ti ile ẹjọ kekere Ebutte-Metta Ọgbẹni Adetayọ Awolesi ju ọdaran kan Mathias Ugwo ẹni ọdun mọkandinlogbọn si ẹwọn ọdun mẹta fun ẹsun ole jija.

Gẹgẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ro fun ile ẹjọ na ni pe ọdaran na Mathias Ugwo lọ ji mọto Bọsi nla kan ti ile iṣẹ Nidogas ni Eko awọn ọlọpa na sọ pe ọna Apapa ni nwọn ti mu ọdaran na ti nwọn si ti mọto Bọsi na gba lọwọ ọdaran na ni oṣu keji ọdun yi.

Ọkunrin ọdaran na ẹniti gbogbo ẹrẹkẹ ati igbọn rẹ kun fun irun Mathias sọ fun adajọ ile ẹjọ na pe on ko jẹbi fun esun ti nwọn fi kan titi nwọn yio fi gbe on si ẹwọn, Adajọ ile ẹjọ na ọgbẹni Awọlẹsi sọ pe ki Mathias Ugwo lọ fi ẹwọn ọdun mẹta jura.

Adele Adajọ ile ẹjọ na gbẹni Aderayọ Awolosi si da Ọdaran na lare fun ẹsun ile fifọ ti nwọn fi kan pe o lọ fọ ile kan ni ọjọ kini oṣu kerin ọdun yi ni deede agogo kan kọja iṣẹju mẹwa ni adugbo Western Avenue Suru Lere eyiti awọn ọlọpa ti budo Ọlọpa Suru-lere fi kan Ọdaran na Ọdaran na si dakẹ jẹjẹ laisọ ọro kan-kan titi awọn Ọlọpa fi mu lọ si ọgba ẹwọn.

# ẸNITI O JI KỌBỌ MẸWA WẸWỌN ỌDUN MEJI

YABA:- Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlogbọn oṣu yi ni ọmọde kunrin kekere ọmọ ọdun mẹfa Ishọla Waidi ti o nlọ si ile ẹkọ kan ni Ebute-Mẹta fi nye adajọ ile ẹjọ kekere ti Yaba pe ọdaran Ọkunrin kan Shehu Ganiyu ba on wọ aṣọ ile ẹkọ on dada ni ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kẹtadiulọgbọ oṣu yi.



Aworan yi ni ti awọn ọmọ ile ẹkọ meji ti ọdaran Shehu gba kọbọ mẹwa lọwọ wọn Awọn ọmọ na ni Ishọla ati Akanni

Ọmọdekunrin na Ishọla Waidi ti o jẹ ọmọ oniwe kini ni ile ẹkọ kan ni Ebu-te-Mẹtta tun fi ye adajọ agba pe lẹhin na ni Shehu Ganiyu ba on tun aṣọ on wọ dada ni Ọdaran na ba tọwọ bọ apo on ti o mu kọbọ marun to wa lapo on ti o si nlọ.

Ishọla Waidi tun fi ye ile ẹjọ pe nigbati on bẹrẹsi kegbe pe ole! ole! ni awọn enia to nlọ l'ẹba on bere si ba on le Ọkunrin Ọdaran na ti nwọn fi mu ui

Ninu ẹniti o jẹri ninu ile ẹjọ na ni ọmọde kekere kan ẹni ọdun mẹfa ti o si tun jẹ ọmọ ile ẹkọ kanna Akanni Afoke fi ye ile ẹjọ pe gẹgẹbi ọdaran ọkunrin na ti ṣe fun ekeji on Ishọla na lo ti ṣe fun on ti o ko kọbọ marun (5d) ti o wa l'apo on lọ bẹ.

Ninu awọn ẹniti to jẹri ni ile ẹjọ na ni ornko awọn ọmọde meji na Ọgbẹni Olushọla Oyinson sọ pe otito ni ọdaran na ji owo awọn ọmọ na nitoripe awọn enia to nlọ lojo ona lo ba awọn ọmọ na mu Shehu Ganiyu ti nwọn si fa ọdaran na l'ọwọ fun on.

Ọgbẹni Olushọla Oyinson sọ pe nigbati awọn enia to ba awọn ọmọde na mu ọdaran na ti nwọn fun on ni on na ba tun tete fa ọdaran na lọmọ awọn Ọlọpa

Nigbati Adajọ ile ẹjọ na sọ pe Ganiyu jebi ẹsun na pe ki o lọ fi Ọdun ẹwọn meji jura pẹlu ki nwọn na bilala mẹfa fun ẹsun meji i.e.

Gẹgẹbi idajọ adajọ agba na sọ pe ki ọdaran na lọ ẹwọn ọdun meji ti o ba ẹsun meji na lọ l'ẹkan ṣoṣo

Adajọ agba ile ẹjọ na tun sọ niuu idajọ rẹ pe ninu kọbọ mẹsan ti nwọn ri ninu apo ọdaran na pe ki nwọn fun Ishọla ni kọ-bọ marun ki nwọn tun fun Afoke ni kọbọ mẹrin yoku ati pe eleyi yio jẹ arikọgbọn fun ọpọlọpọ awọn ole to ma nhu iru iwa bẹ mọ awọn ọmọ kekere to sẹsẹ bẹre si lọ si ile ẹkọ Shehu Ganiyu si gbe itiju rẹ lẹ ọgba ẹwọn

LATI OJU EWE KINI

Siwaju si Alhaji Aminu ka-no tun sọ pe ohun to fi jẹ pe o tọ lati le pa awọn ẹgbẹ oṣelu to wa ni ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria pọ. papa ni pe lati le tete jẹ ki ọplọpọ awọn ẹgbẹ oṣelu to wa ni ipilẹ na I. din ku diẹ ki idaru-dadọ le wa si opin ni orilẹ ede Naijiria.

Alhaji Aminu Kono tun sọ pe ohun to on fi sọ pe ki nwọn din ẹgbẹ oṣelu to wa ni ilẹ Naijiria ku ni pe ki awọn enia orilẹ ede Naijiria le mọ ẹgbẹ oṣelu toyẹ ki wọn dibo fun lasi koidibo ati lati le mọ iru gbẹ oṣel to le tẹ awọn enia tilẹ Naijiria l'ọrun lẹhin idibo si ile gbimọ aṣofin apapọ.

Ninu iwe kan ti Alufa J A Akinyẹmi ọkan ninu aWọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ile Igbimọ Aṣofin ti apapọ Ijọba Naijiria ṣọ ninu iwe rẹ lati iwosan ile ti Unifasiti ni Ibadan ni ibi ti Alufa Akinyẹmi ti ntọju ara rẹ fun ara to fi gbọgbẹ nigbati awọn ẹhanna ẹgbẹ ẹgbẹ Oṣelu kan kọlu laipẹ yi sọpe: on fẹ ki awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Ijẹ-sha mura gidgidi lati lebori awọn ẹgbẹ Oṣelu kan ti nwọn fi agbara nṣe Ijọba ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Alakoso ẹgbẹ Afẹnifẹre Ọgbẹni J. O. Lawanson sọ ninu ọrọ rẹ nibi ipade ti oba awọn ọmọ Afẹnifẹre sọ nigbati o njiṣẹ Alufa Akinyẹmi fun awọn ọmọ ẹgbẹ nani Ilesha pe ki gbo-gbo Olukuluku awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilẹ Ilesha lọ mura gidi ati pe ohun to le gbe Oloye Awolọwọ jade bayini ibo didi.

Ọgbẹni Lawanson si tun rọ awọn ọmọ ẹgbẹ na lati lọ mura ki nwọn dibo fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ lasiko idibo ile Igbimọ Aṣofin ti apapọ Ijọba.

Ọgbẹni Lawanson sọ pe ohun to le gbe Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre kuro l'ọgba ẹwọn ni yẹn ki ipade ẹgbẹ na to lọ si opin, awọn ọmọ ẹgbẹ iAfẹnifẹre sọ pe nwọn ko ni gbẹkẹle lori idajọ Oloye Awolọwọ eyiti ile ẹjọ giga ju'ọ ilẹ Naijiria kọ ẹbẹ ẹwọn Ọdun mẹwa rẹ silẹ

Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 29/7/64.